# Adébáyọ̀ Fálétí

Moses O. Mabayọjẹ
New York University
mm9550@nyu.edu

Adébáyọ̀ baba Adébọ́lá! Baba Ọlámilékan!!
Mo ń pè ọ́ lóhùn arò, o ò sì jẹ́ mi mọ́.
Òkú ń yan ọmọ rẹ̀ lódì, atòntorí ọmọ ọlọ́mọ.
Ìwọ náà kọ́, ikú ló kúkú mẹ́ja kákò bẹ́ẹ̀.
Níjọ́ iṣu kú, mo dabọ n ò jiyán
Níjọ́ àgbàdo kú, mo dabọ n ò jẹ̀kọ
Níjọ́ ajá mi kú, mo dabọ n ò jẹran abíríkolo
Ẹran abíríkolo, àbẹ̀gbẹ́ mọ̀ndẹ̀

Níjọ́ táa kú làá yí padà dère àgbéjó
Níjọ́ tá kú làá yí padà dère àgbégẹ̀gẹ
Ọmọ ènìyàn, wọn ò sunwọ̀n tán láàyè
Adébáyọ̀ Fálétí sunwọ̀n láàyè
Ó tún sunwọ̀n níwàwun
Níjọ́ ajá bá dọbẹ̀, níí jẹ̀kọ jàáyè rẹ̀ lọ
Ẹ wá wòkú ewúrẹ́ ọmọ Dúrówadé Àyìnkẹ
Bó ṣe dìlù, tó tún wá ń fọhùn bí ènìyàn!
Ikú ò débi ọ̀rọ̀ dùn wá dé, ọmọ Àkànbí
Báa bá mọ̀ pérìn ọmọ Jòsẹ́ẹ̀fù ó wọ́
Bó bá ṣeé ṣe, à bá dì mórù erin
Ṣùgbọ́n lílọ àjànàkú ò náání ìtàkùn
Kùrukùru àjànàkú bókè ṣe,
Erin ọkọ Motẹ́níọlá ṣe bẹ́ẹ̀, ó gòkè àlọ̀
Àìbíni sínú ọlá kì í dínàa kádàrá
Atàpáta dìde kàn lè jẹ́ kìkì ìjìràko ni
Ayé Fálétí fèyí ṣàpẹrẹ rere fún wa
Àbí ká ṣiṣẹ́ ká tó ránraẹni nílé ìwé ni ká wí ni?

Tàbí ká kàwó ọ̀hún lákàrosẹ̀ ká tó rówó ná?
Ká ti Yunifásítì Dakar padà sí ti Ìbàdàn?
Àṣẹ̀ṣẹ̀ wọ́n ológbò rúngbàdo kó tó tékuú pa
Ṣùgbọ́n ìrèké ọmọ Fálétí ò ní ibùdó
Ibi gbogbo ló gbalàgbára ọmọ Aláyìnkẹ́
Kò síbi Adébáyọ̀ fẹsẹ̀ tẹ̀ lókè eèpẹ
Tí ò di sárúmọ́ tí ń ká wọn sàwáwù léyín jẹ
Àbínibí ṣẹ̀gbọ́n àwọ̀ṣe lọ̀rọ̀ ọmọ Àkànbí
O kúkú ti sọ pé àṣejù ohun táa yàn laáàyò
Níí múni dìlúmọ̀ọ́ká láàrin àwùjọ
Kò sóhun ọmọ Fálétí dáwọ́ lé lókè eèpẹ̀
Tí ò nípò aṣaájú bí akọ́ṣẹ́mọṣẹ́
Ṣebí Ajíṣebí Ọ̀yọ́ làá kúkú rí lọ́jọ́kọ́jọ́
Ọ̀yọ́ kò ní ṣe bí ẹnì kọ̀ọ̀kan
Adébáyọ̀ pegedé, ó fi gbọ̀rọ̀ jẹkà
Mélòó làá kà nínú eyín bàbá oníkọ̀nkọ̀sọ̀
Ó jẹ ọgọ́ta gbàǹja, ogójì rẹ̀ sì há a léyín pátá?
Ṣé tìmọ̀ àṣà, òwe àti ìsàré láti pínnísín ni ká wí?
Ṣé teré orí-ìtàgé ni tàbí toníṣe ní kíkọ ni ò tó ròyìn ni?
Tàbí taṣaájú nínú ìtàn àròsọ àpilẹ̀kọ tí ń dáni lárayá?
Láìfigbá kankan yọ tẹ̀kọ ìwà dànù?
Fálétí làwọn akéwì yòókù ń wárí fún
Wọ́n ní "Gúnugún Adébáyọ̀ làwọn kọ́kọ́ rí
Káwọn ó tó máa dáṣà gbàguruyẹ gbàguruyẹ
Àkàlà ọmọ Fálétí làwọn kọ́kọ́ mọ
Káwọn ó tó máa dáṣà bàgẹ̀bàgẹ̀"
Adébáyọ̀ Fálétí lọ̀pọ̀ akéwì fi ṣàwòkọ̀ṣe ìmọ̀
Kí wọn ó tó máa dáṣà ewì kíké
Ẹ jẹ́ ká fò fẹ̀rẹ̀ dé gbogbo ibi Adébáyọ̀ Fálétí ti ṣiṣẹ
Kò séyìí tó ṣe níbẹ̀ tí kò ti ṣàṣeyege
WNTV/WNBS ló kọ́kọ́ ti nawọ́jà rẹ̀ síṣẹ́ ìròyìn
Adébáyọ̀ ló kọ́ká gbéròyìn sójú afẹ́fẹ
Akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ tí ń gbénú àpótí fọhùn bí àǹjànnú
Ó tún yà sí eré orí-ìtàgé, ó tún rọ́wọ́ mú
Orí kì í gbèran ọ̀lẹ bí alágbára
Adámáleṣe l'òrìṣà ò fi gbè wọ́n
Adébáyọ̀ fìwà kúnṣẹ́ àṣekára
Ìjọba ìbílẹ̀, ti ìpínlẹ̀, ti àpapọ̀ àtàwọn yunifásítì ńlá ńlá
Gbogbo wọn lá ń fipò atòyè wá alàgbà kiri
Bẹ̀ẹ̀ bá rántí ìyókù, ti MAMSA ńkọ́?
Onírèsé Adébáyọ̀ ọmọ Fálétí kó fíngbá mọ́

Gbogbo èyí tó ti fín kò lè parun
Kò sẹ́ni tí ò ní kú, kò sẹ́ni tí ò ní rọ̀run
Kò sẹ́ni tóko baba rẹ̀ ò ní dìgbòrò
ọ̀run dẹ̀dẹ́ ni kó sáà má kánjú rárá
Gbogbo wa là ń bọ̀ leẹ́yì̀n pẹ̀sẹ̀pẹ̀sẹ
*Orin*
*Lile:* Kúdère, ọmọ Fálétí ò jẹ́ wa mọ́ o
Àá ṣeé peni, tí kì í ṣeé jẹ́?
O di ewúrẹ́ jiléjilé
O di àgùtàn jimọ̀jimọ̀
O di àláàmu pẹ̀bẹ́, tí kiri ẹ̀gbẹ́ ògiri
*Egbe:* Kúdère, ọmọ Fálétí ò jẹ́ wa mọ́ o
Àá ṣeé peni, tí kì í ṣeé jẹ́?
*Lile:* Ó dàrìnnàkò, ó dojú àlá!
Ó di ká rẹ́ni tó jọni, réèyàn tó jọ̀ọ̀yàn
Ó di ká bímọ tó jọ baba ẹni ká pé Babátúndé ni
*Egbe:* Kúdère, ọmọ Fálétí ò jẹ́ wa mọ́ o
Àá ṣeé peni, tí kì í ṣeé jẹ́?

